Ẹni ti o ba ṣe aluwala gẹgẹ bi mo ṣe ṣe aluwala mi yii lẹyin naa o wa ki rakah meji ti ko ba ẹmi rẹ sọrọ nibi mejeeji, Ọlọhun yoo fori nnkan ti o ṣíwájú ninu ẹṣẹ rẹ jin in

Lati ọdọ Humraan ẹru Uthman ọmọ ‘Affan pé o ri Uthman ọmọ ‘Affan ti o beere fun omi aluwala, o ti ọwọ rẹ mejeeji bọ inu igba rẹ, o fọ mejeeji lẹẹmẹta, lẹyin naa o ti ọwọ rẹ ọtun bọ inu omi aluwala, lẹyin naa o fi omi yọ ẹnu rẹ o si fin in simu o si fin in síta, lẹyin naa o fọ oju rẹ lẹẹmẹta, ati ọwọ rẹ mejeeji titi de igunpa rẹ mejeeji lẹẹmẹta, lẹyin naa o pa ori rẹ, lẹyin naa o fọ gbogbo ẹsẹ rẹ lẹẹmẹta, lẹyin naa o sọ pe: Mo ri Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti o n ṣe aluwala gẹgẹ bi mo ṣe ṣe aluwala mi yìí, o wa sọ pe: “Ẹni ti o ba ṣe aluwala gẹgẹ bi mo ṣe ṣe aluwala mi yii lẹyin naa o wa ki rakah meji ti ko ba ẹmi rẹ sọrọ nibi mejeeji, Ọlọhun yoo fori nnkan ti o ṣíwájú ninu ẹṣẹ rẹ jin in”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Uthman- ki Ọlọhun yọnu si i- kọ wa ni bi Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣe maa n ṣe aluwala pẹlu oju ọna fifi ṣe iṣẹ ṣe; ki o le baa kun ni alaye, lẹyin naa o beere fun omi ninu igba, o wa da a si ọwọ rẹ mejeeji lẹẹmẹta, lẹyin naa o ti ọwọ rẹ ọtun bọ inu igba, o fi bu omi o si da a si ẹnu rẹ o si mu u jáde, lẹyin naa o fin omi fun ara rẹ sinu imu rẹ, lẹyin naa o mu u sita o si fin in síta, lẹyin naa o fọ oju rẹ lẹẹmẹta, lẹyin naa o fọ ọwọ rẹ mejeeji pẹlu igunpa rẹ mejeeji lẹẹmẹta, lẹyin naa o mu ọwọ rẹ re kọja lori ori rẹ ni nnkan ti o tutu fun omi lẹẹkan, lẹyin naa o fọ ẹsẹ rẹ mejeeji pẹlu kokosẹ rẹ mejeeji lẹẹmẹta. Nigba ti Uthman- ki Ọlọhun yọnu si i- pari o sọ fun wọn pe dajudaju oun ri Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti o ṣe aluwala gẹgẹ bii aluwala yii, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa fun wọn ni iro idunnu pe dajudaju ẹni ti o ba ṣe aluwala gẹgẹ bii aluwala rẹ, ti o wa ki rakah meji, ni ẹni ti o n wa ni irẹlẹ ti ọkan rẹ si wa lori irun niwaju Oluwa rẹ- Alagbara ti O gbọnngbọn- nibi mejeeji, dajudaju Ọlọhun yoo san an lẹsan lori aluwala ti o pe yii ati irun ti o mọ kanga yii pẹlu aforijin nnkan ti o ṣíwájú ninu awọn ẹṣẹ rẹ.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3313